# IP Ẹ̀yà 6 ( IPv6 ) àgbékalẹ̀ àwọn àdírẹ́ẹ̀sì wọn

## 1 Ọ̀rọ̀ Ìṣáájú

Àwọn àlàyé wọ̀nyìí máa fún wa ni ìgbékalẹ̀ àdírẹẹ̀ẹ̀sì ìfẹnukò.

## 2 IPv6 àdírẹ́ẹ̀sì

Àwọn àdírẹ́ẹ̀sì IPv6 wà lórí bíìtì 128 fún àwọn atọ́kùn.
Irúfẹ́ àdírẹ́ẹ̀sì atọ́kùn mẹ́ta ló wà :

1. Unicast : Àdírẹ́ẹ̀sì ìtànkalẹ̀ fún ojú kan
   Máa ń tọ́ka sí atọ́kùn kan, èdìdì tí a bá fìránṣẹ́ pẹ̀lú àdírẹ́ẹ̀sì unicast máa dórí atọ́kùn ìtọ́kasí.
2. Anycast : Àdírẹ́ẹ̀sì ìtànkalẹ̀ ojú kan nínú púpọ̀
   Máa tọ́ka sí àwọn ìjọ atọ́kùn (àwọn atọ́kùn ti kókó kan tí wọn sì yàtọ̀ ).
   Èdìdì tí a bá fìránṣẹ́ sí àdírẹ́ẹ̀sì anycast kan máa dórí atọ́kùn tí kò jìnà, alànà ló máa ṣedíwọ̀n ọ̀nà yìí.
3. Multicast : Ìtànkalẹ̀
   Máa tọ́ka sí ìjọ àwọn atọ́kùn ( wọ́n wà nínú àwọn kókó tó yàtọ̀ ).
   Èdìdì tí a bá fìránṣẹ́ pẹ̀lú àdírẹ́ẹ̀sì multicast máa dórí àwọn atọ́kùn wọ̀nyìí.

Kò sí àdírẹ̀ẹ̀sì ìtànkalẹ̀ gbogbogbò pẹ̀lú IPv6, a parọ iṣẹ́ wọn pẹ́lú àdírẹ́ẹ̀sì multicast. Nínú IPv6 àwọn òdo àti àwọn oókan jẹ́ àwọn oǹkaye tó bá òfin mú fún gbogbo ààyè.

### 2.1 Àwòṣe ìlò àdírẹ́ẹ̀sì

Àwọn atọ́kùn ni a máa ń lò àdírẹ́ẹ̀sì IPv6 fún, a kìí lò wọn fún àwọn kókó àsopọ̀.
Àdírẹ́ẹ̀sì unicast máa tọ́ka sí atọ́kùn kan tó wà nínú kókó kan, tó jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn atọ́kùn kókó náà, a lè lò àdírẹ́ẹ̀sì unicast kan fi ṣàfidámọ̀ kókó náà.

Gbogbo àwọn atọ́kùn ní láti ní àdírẹ́ẹ̀sì unicast kan tó jẹ́ àsopọ̀ agbègbè, a lè fún atọ́kùn ni àdírẹ́ẹ̀sì kan; a lè fún un ni àdírẹ́ẹ̀sì méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ, ti irúfẹ́ wọn yàtọ̀ ( unicast, anycast, multicast ) tàbí pẹ̀lú iyekíye oǹkaye fífò.
Nígbà tí òpin àwọn àdírẹ́ẹ̀sì unicast bá jù ti agbègbè lọ, kò pọndandan ká fún atọ́kùn kan ni àdírẹ́ẹ̀sì yìí tí kìí bá ṣe ti èdìdì tó kúrò tàbí tí ń lọ sí agbègbè tí kìí ṣe ti ẹgbẹ́. Èyí máa wúlò nígbà mì ín fún àsopọ̀ ojú-àmì sí ojú-àmì. Àmọ́ sùgbọ́n kan wà níbẹ̀ :
IPv6 jẹ́ ìtẹ̀síwájú IPv4 tí àfòmọ́ àsopọ̀ abẹ́nu somọ́ àsopọ̀ kan. Àwọn àfòmọ́ alásopọ̀ abẹ́nu púpọ̀ lè wà ni sísopọ̀ mọ́ àsopọ̀ kan.

### 2.2 Kíkọ àyọkà àdírẹ́ẹ̀sì

Ọ̀nà mẹ́ta ni a máa ń ṣàfihàn àyọkà àdírẹ́ẹ̀sì IPv6.
ìrísí tí a máa ń lò ni :

1) X:X:X:X:X:X:X:X tí àwọn X jẹ́ oǹkaye oní mẹ́rindínlógun pẹ̀lú bíìtì 16.

**Àpẹẹrẹ**

FEDC:BA98:7654:3210:FDEC:BA98:7654:3210
1080:0:0:0:8:800:200C:417A

Kìí ṣe dandan ká kọ àwọn òdo tí kò níí ìtúmọ̀ sínú àwọn ààyè kọ̀ọ̀kan , àmọ́ oǹkaye kan láti wà nínú ààyè kọ̀ọ̀kan.

2) Ọ̀nà ti a fi kọ àdírẹ́ẹ̀sì IPv6 máa ń gùn jù, nígbà gbogbo tí àwọn 0 bá wà láàrin àyọkà àdírẹ́ẹ̀sì yìí a máa lò àmi :: fi ṣèfúnpọ̀ àyọkà yìí. ": :" túmọ̀ sí bíìtì 16 tó dọ́gba mọ́ 0, ẹ̀kan ni ": :" lè wà nínú àdírẹ́ẹ̀sì. A tún lè lò ": :" fi ṣèfúnpọ̀ àwọn 0 tí ìbẹ̀rẹ̀ àti ti ìkẹ́yìn.

**Àpẹẹrẹ**

1080:0:0:0:8:800:200C:417A Àdírẹ́ẹ̀sì IP

FF01:0:0:0:0:0:0:101 Àdírẹ́ẹ̀sì multicast

0:0:0:0:0:0:0:1 Àdírẹ́ẹ̀sì Ìpari c

òpin

0:0:0:0:0:0:0:0 Àdírẹ́ẹ̀sì

A tún lè kọ wọn lọ́nà yìí :

1080::8:800:200C:417A

FF01:0:101

::1

::

3) Fún lílò àdírẹ́ẹ̀sì IPv6 lọ́nà ìdàpọ̀ IPv6 àti IPv4 a máa lò kíkọ yìí

X:X:X:X:X:X:d:d:d:d tí "X" jẹ́ oǹkaye onímẹ́rindínlógun tí d sì jẹ́ oǹkaye tí a máa lò pẹ̀lú IPv4 ( oǹkaye oníwẹ́wa )

**Àpẹẹrẹ**

0:0:0:0:0:0:13.1.68.3

0:0:0:0:0:FFFF:129.144.52.38 tàbí

::13.1.68.3

::FFFF:129.144.52.38

## 2.3 Àyọkà tí a sàfihàn pẹ̀lú àfomọ́ àdírẹ́ẹ̀sì

A máa ń ṣàfihàn àyọkà àdírẹ́ẹ̀sì àfòmọ́ IPv6 bí a tí ń kọ ti IPv4 lọ́nà CIDR.

Ìrísí :

Àdírẹ̀ẹ̀sì IPv6 / gígùn àfòmọ́ :

Àdírẹ̀ẹ̀sì ipv6  :  Àwọn èyí tí a rí lókè

Gígùn àfòmọ́  :  Oǹkaye onímẹ́wa tí ń tọ́ka sí iye bíìtì agbègbè tó wà ni sísopọ̀ tí ń fi àfòmọ́ hàn.

Àwọn àpẹẹrẹ tó wà nísàlẹ́ jẹ́ àfihàn àfòmọ́ oní bíìtì 60 tó bá òfin mu :

Àfòmọ́  12B000000000CD3

12AB:0000:0000:CD3:0000:0000:0000:0000/60

12AB:0:0:CD3::/60

Àwọn kíkọ wọ̀nyìí ò bófin mu :

12AB:0:0:CD3/60
12AB::CD30 /60
12AB::CD3/60

Nígbà tí a bá fẹ́ kọ àdírẹ̀ẹ̀sì kókó pẹ̀lú àdírẹ̀ẹ̀sì àfòmọ́ kókó yìí ( bíi àpẹẹrẹ àlásopọ̀ abẹ́nu ) a lè kọ méjèjì báyìí :

| | |
|---|---|
| Àdírẹ̀ẹ̀sì kókó | 12AB:0:0:CD30:123:4567:89AB:CDEF |
| alásopọ̀ abẹ́nu | 12AB:0:0CD30::/60 |
| Ní ṣokí | 12AB:0:0:CD30:123:4567:89B:CDEF / 60 |

## 2.4 Ìṣàfihàn àdírẹ̀ẹ̀sì àkànṣe

Àwọn àdírẹ̀ẹ̀sì àkànṣe máa  ń tọ́ka sí àwọn bíìtì nínú àdírẹ̀ẹ̀sì. Àwọn ààyè tí àwọn bíìtì wọ̀nyìí wà nínú wọn ni a ń pè ni ìrísí Àfòmọ́ (FP ), àwọn kíkọ wọn ni wọ̀nyìí.

| Ìpín | Àfòmọ́ ( àbéjì ) | Àjákù ( ààyè àdírẹ̀ẹ̀sì ) |
|---|---|---|
| **Ìfipamọ** | **0000 0000** | **1/256** |
| **Àìmúlò** | **0000 0001** | **1/256** |
| **Ìfipamọ fún Ìpín NSAP** | **0000 001** | **1/128** |
| **Ìfipamọ fún Ìpín IPX** | **0000 010** | **1/128** |
| **Àìmúlò** | **0000 011** | **1/128** |
| **Àìmúlò** | **0000 1** | **1/32** |
| **Àìmúlò** | **0001** | **1/16** |

| | | |
|---|---|---|
| **Àdíréẹ̀sì káríayé Unicast Alápàpọ̀** | **001** | **1/8** |
| **Àìmúlò** | **010** | **1/8** |
| **Àìmúlò** | **011** | **1/8** |
| **Àìmúlò** | **100** | **1/8** |
| **Àìmúlò** | **101** | **1/8** |
| **Àìmúlò** | **110** | **1/8** |
| **Àìmúlò** | **1110** | **1/16** |
| **Àìmúlò** | **1111 0** | **1/32** |
| **Àìmúlò** | **1111 10** | **1/64** |
| **Àìmúlò** | **1111 110** | **1/128** |
| **Àìmúlò** | **1111 1110 0** | **1/512** |
| **Àdíréẹ̀sí Unicast àsopọ̀-àgbègbè** | **1111 1110 10** | **1/1024** |
| **Àdíréẹ̀sí Unicast ojú-òpó** | **1111 1110 11** | **1/1024** |
| **Àdíréẹ̀sí Multicast** | **1111 1111** | **1/256** |

**Àkíyèsí**
A máa lò àwọn àdíréẹ̀sì àìmúlò, ìpariòpin àti àwọn àdíréẹ̀sì IPv6 pẹ̀lú àṣèfibọ̀ àwọn àdíréẹ̀sì IPv4 làìsí ìrísí àfòmọ́ 0000 0000 nínú wọn.

Bíìtì 64 ni ń ṣàtọ́ka àtọkùn ( ní ìrísí EUI-64 ) àwọn àdíréẹ̀sì aláfòmọ́ irú 001 dé 111 làìsí àdíréẹ̀sì ìtànkalẹ̀ ( 1111 1111 ) nínú rẹ̀; a máa ṣàlàyé wọn nínú abala 2.5.1.

A máa ń lò àwọn àdíréẹ̀sì wọ̀nyìí fún àdíréẹ̀sì agbègbè àti ti ìtànkalẹ̀ káríayé. A fi àlàfo kalẹ̀ fún àwọn àdíréẹ̀sì NASP àti IPX, a ò lò àwọn àdíréẹ̀sì tó kù tí wọn á wúlò lọ́jọ́ wájú. 15% àwọn àdíréẹ̀sì ni a ń lè lọ̀wọ́lọ̀wọ́, àwọn yòkù máa jẹ́ lílò lọ́jọ́ wájú.
Àwọn bíìtì wájú tó ní agbára ni a máa ń fi mọ̀ ìyàtọ̀ nínú àdíréẹ̀sì unicast tàbí multicast. Oǹkaye FF ( 11111111 ) máa ń tọ́ka sí àdíréẹ̀sì multicast. A máa lò àdíréẹ̀sì anycast bíi unicast.

## 2.5 Àdíréẹ̀sì unicast

A lè ṣàtòpọ̀ àdíréẹ̀sì unicast kan pẹ̀lú àwọn bíìtì àtòpọ̀, àwọn ìbójú bíi ti IPv4 tó jẹ́ ìfísọ̀nà láàrin agbègbè ìkópa láìsí ọ̀wọ́ agbègbè ìfisọ̀nà.

Ọ̀nà púpọ̀ ni a máa ń fi fún atọ̀kùn ni àdíréẹ̀sì nínú IPv6 pẹ̀lú àwọn àdíréẹ̀sì unicast, NASP, IPX, ojú-òpó agbègbè, àsopọ̀ agbègbè àti ti ẹ̀rọ kọ̀ǹpútà, tó sì báramu pẹ̀lú IPv4. A máa ṣàfikún ní wájú.

Ó seé ṣe kí kókó àsopọ̀ kan mọ̀ ètò gan an àdíréẹ̀sì IPv6 tàbí ní ìwọ̀nba, èyí tó jẹmọ ipa tí ń kó ( Bíi àpẹẹrẹ kọ̀ǹpútà kójú alànà ) lẹ́nu kan kókó àsopọ̀ kan, lè rí àdíréẹ̀sì unicast kan bíi àìlétò ).

```
|                        128 bits                        |
+--------------------------------------------------------+
|                      Kókó àsopọ̀                        |
+--------------------------------------------------------+
```

Ẹrọ kọ́ńpútà àtọ́wọ́da kan ( àmọ̀ tí kò ní agbára jù ) lè máa ṣàkíyèsí àwọn àfòmọ́ alásopọ̀ abẹ́nu tó somọ ọ́, tí àwọn àdírẹ́ẹ̀sì tó yàtọ̀ ní àwọn oǹkaye n tó yàtọ̀.

```
|                      bíìtì  n                   |   128-n bits   |
+-------------------------------------------------+----------------+
|            àfòmọ́alásopọ̀abẹ́nu                   | atọ́kùn ID    |
+-------------------------------------------------+----------------+
```

Àwọn ẹ̀rọ kọ́ńpútà àtọ́wọ́dá tó tún ní agbára, lè mọ̀ àwọn ìpin nínú àdírẹ́ẹ̀sì unicast.
Nígbà tí àwọn alànà tí kò níí agbára láti ní ìmọ̀ ètò àdírẹ́ẹ̀sì IPv6 unicast, àwọn alànà máa ń nímọ̀ ní àwọn ìpele ààlà fún ìfẹ́nukò ìfisọ́nà. Àwọn ààlà máa ń yàtọ̀ láàrin àwọn alànà pẹ̀lú ìpo wọn.

## 2.5.1 **Àwọn atọ́kasí atọ́kùn**

A máa ń lò àwọn atọ́kasí àdírẹ́ẹ̀sì unicast IPv6 fi ṣèdámọ̀ atọ́kùn kan nínú àsọpọ̀, tí kò sì pé méjì. Wọ́n tún lè jẹ́ atọ́kùn ẹyọ kan nínú ààlà wájú.
Ní ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ìgbà atọ́kasí atọ́kùn máa ń ní àdírẹ́ẹ̀sì kannáà pẹ̀lú ti ìpele àsopọ̀. A lè lò àdírẹ́ẹ̀sì atọ́kasí atọ́kùn kannáà fún atọ́kùn púpọ̀ lórí kókó àsopọ̀ kan.

**Àkíyèsí** ni pé, nígbà tí a bá tọ́kasí atọ́kùn púpọ̀ tó somọ́ kókó kannáà pẹ̀lú atọ́ka kan, èyí ò ní pé kí a máa mọ̀ atọ́kùn kan sí omií.
Nínú àwọn ìrísí àfomọ́ púpọ̀ tí a rí ní wájú atọ́ka láti ní bíìtì 64 tí a sì ṣeé ètò ẹ, lọ́nà ìfẹ́nukò IEEE EUI-64 ( aṣèdámọ̀ ). Àwọn atọ́ka atọ́kùn tí ń lò ìfẹ́nukò EUI-64 lè ní fífò káríayé ti ( àfidámọ̀ ) tí àmì ìdánilójú bá wà ( àpẹẹrẹ bíìtì MAC ) tàbí fífò agbègbè tí àmì ìdánilójú kò bá sí ( bíi àpẹẹrẹ , àtẹ̀lé àsopọ̀, èbúté ọ̀nà-abẹ́lẹ̀ ...).
Ó pọndandan, kí bíìtì "u" bíìtì kéríayé / agbègbè nínú àfẹ́nukò lè ṣeé yípadà tí a bá ṣètò atọ́ka atọ́kùn. Bíìtì máa jẹ́ 1 fún òpin káríayé, 0 fún òpin agbègbè. Àwọn báìtì mẹ́ta àkọ́kọ́ ti EUI-64 atọ́ka ni wọ̀nyìí.

```
 0       0 0       1 1       2
|0       7 8       5 6       3|
+----+----+----+----+----+----+
|cccc|ccug|cccc|cccc|cccc|cccc|
+----+----+----+----+----+----+
```

A kọ ọ́ lọ́nà ètò àwọn ìlànà kíkọ bíìtì íntẹ́nẹ́ẹ̀tì, "u" jẹ́ bíìtì káríayé / agbègbè, "g" jẹ́ bíìtì olúkúlùkù / Ìjọ, "c" jẹ́ àwọn bíìtì adámọ̀ iléṣẹ́.
Ọ̀nà tí a fi ṣẹ̀dá atọ́ka atọ́kùn tó dúró sórí EUI-64 wà ní Àfikún A.

Ìgbìyànjú àwọn alákoso ẹ̀rọ fi ṣe ìyípadà bíìtì "u" nígbà tí a bá ṣàtọ́ka atọ́kùn ni kí wọn bá a ṣàtòpọ̀ àwọn atọ́ka òpin agbègbè nígbà tí àmì ìdánilójú àfidámọ̀ ẹ̀rọ kò bá sí. Bí tí a máa rí fún àwọn àsopọ̀ àtòtẹ̀lé àwọn èbúté ọ̀nà abẹ́lẹ̀... Àfirọpò ni kò bá ti jẹ́ ìrísí 0200:0:0:1 èyí ti á fi jẹ́ onírọ̀rùn ::1, ::2, .etc
Lílò bíìtì káriayé/agbègbè nínú atọ́ka IEEE EUI-64 á jẹ́ àǹfààní fún ìtẹ̀síwájú ìmọ̀ ẹ̀rọ láti lò atọ́ka atọ́kùn pẹ̀lú fífò káríayé.
Àwọn àlàyé ìṣẹ̀dá àwọn atọ́ka atọ́kùn wà nínú àkọlẹ̀ bíi "IPv6 over Ethernet" , "IPv6 over FDDI"

## 2.5.2 Àwọn àdírẹ́ẹ̀sì tí a ò sọ nípa wọn

Àdírẹ́ẹ̀  0:0:0:0:0:0:0:0 tí a tún ń pè ni àdírẹ́ẹ̀sì tí kò níí àlàyé. A ò gbọdọ fún kókó kan ni àdírẹ́ẹ̀sì yìí, n ṣàlàyé ài sí àdírẹ́ẹ̀sì.
Bí àpẹẹrẹ kọ̀ńpútà tí kò mọ̀ àdírẹ́ẹ̀sì rẹ̀ lè lò ó láti fi èdìdì IPv6 ránṣẹ́ kó tó wa mọ̀ àdírẹ́ẹ̀sì rẹ̀. A ò níí láti lò adírẹ́ẹ̀sì yìí fún èbúté kan, tàbí fún alànà kan

## 2.5.3 Àdírẹ́ẹ̀sì ìparíòpin

Àdírẹ́ẹ̀sì ìpariòpin  0:0:0:0:0:0:0:1 tí a ń pè ni “loopback”. Kókó kan máa ń lò ó fi sèfiránṣẹ́ èdìdì si ara rẹ̀. Adírẹ́ẹ̀sì ìpariòpin ò ṣe lò fún nǹkan mì ín mọ́.

## 2.5.4 Àdírẹ́ẹ̀sì IPv6 pẹ̀lú ìfibọ̀ IPv4

Ètò ìyípdà IPv6[ TRAN ] pẹ̀lú àlàkalẹ̀ lórí àwọn kọ̀ńpútà àti àwọn alànà tí ń fún wa ni àǹfààní láti ṣàfisọ́nà àládaṣe lọ́nà abẹ́lẹ̀ àwọn èdìdì IPv6 sórí amáyédẹrùn ìfisọ́nà IPv4.
Àwọn kókó àsopọ̀ tí ń lò àdírẹ́ẹ̀sì IPv6 tó ní àdírẹ́ẹ̀sì tó pari pẹ̀lú àdírẹ́ẹ̀sì IPv4 lẹ́yìn.
Ìrísí àwọn àdírẹ́ẹ̀sì náà ni :

```
|                bìítì 80                | 16 |      32 bits        |
+--------------------------------------+----------------------------+
|0000..............................0000|0000|     Àdírẹ́ẹ̀sì IPv4       |
+--------------------------------------+----+-----------------------+
```

 A tún ṣàlàyé irúfẹ̀ àdírẹ́ẹ̀sì IPv6 pẹ̀lú ìfibọ̀ IPv4. A máa ń lò àdírẹ́ẹ̀sì yìí fún kókó àsopọ̀ tí ń lò IPv4 nìkan làìsí IPv6 nínú ẹ. A máa ń pè àdírẹ́ẹ̀sì yìí ni IPv6 bíi ìrísí.

```
|               bìítì 80                 | 16 |      bìítì          |
+--------------------------------------+----------------------------+
|0000..............................0000|FFFF|     Àdírẹ́ẹ̀sì IPv4       |
+--------------------------------------+----+-----------------------+
```

## 2.2.5  NSAP

A tún bẹ̀rẹ̀

## 2.5.6  Àdírẹ́ẹ̀sì IPX

Àfisojú àdírẹ́ẹ̀sì IPX nínú IPv6 níí

```
|   7   |                  bìítì 121                                |
+-------+-----------------------------------------------------------+
|0000010|                Àlàyé ní wájú                              |
+-------+-----------------------------------------------------------+
```

Isẹ́ ń lórí  :
Àlàyé iṣẹ́ àkànṣe, ìwúrí àti ìmúlò ẹ.

## 2.5.7  Àdírẹ́ẹ̀sì unicast alákànpọ̀ gbogbo

A ṣàlàyé àdírẹ́ẹ̀sì alákànpọ̀ yìí sínú àkọlẹ̀ [ AGGR ].
Ìrísí àdírẹ́ẹ̀sì máa ń fún àwọn iléṣẹ́ olùpèsè ìgbà yìí láǹfààní láti máa lò àdírẹ́ẹ̀sì yìí pẹ̀lú omìí tí

a pè ni “exchanges” . àpàpọ àwọn méjèjì máa ń jẹ́ kí ìfisọ́nà rọrùn fún àwọn ojú-òpó méjèjì fi ṣàsopọ̀ pẹ̀lú àwọn olùpèsè àti “exchanges”. Àwọn ojú-òpó máa ń ní àǹfààní láti ṣàsopọ̀ pẹ̀lú ara wọn.

Ìrísí àdírẹ́ẹ̀sì níí.

```
| 3|  13 | 8 |    24    |    16    |           64 bits              |
+--+-----+---+--------+--------+--------------------------------+
|FP| TLA |RES|  NLA   |  SLA   |          atọ́kùn ID              |
|  | ID  |   |  ID    |  ID    |                                |
+--+-----+---+--------+--------+--------------------------------+
```

001 Bíìtì 3 àfomọ́ fún àdírẹ́ẹ̀sì unicast alákanpọ̀ gbogbo

TLA ID Atọ́ka sí àkànpọ̀ ìpele gíga ( Àwọn àgbájọ apàṣẹ ìforúkọsílẹ̀ gíga jù íntẹ́nẹ́tì )

SLA ID Atọ́ka sí àkànpọ̀ ìpele kèjì

ÀTỌ̀KÙN ID Atọ́ka sí atọ́kùn

```
FP           Format Prefix (001)
      TLA ID       Top-Level Aggregation Identifier
      RES          Reserved for future use
      NLA ID       Next-Level Aggregation Identifier
      SLA ID       Site-Level Aggregation Identifier
      INTERFACE ID Interface Identifier
```

## 2.5.8 Ìmúlò IPv6 ní agbègbè

Oríṣi àdírẹ́ẹ̀sì unicast ìmúlò agbègbè méjì ló wà : Tí àsopọ́-agbègbè àti ti ojú-òpó agbègbè.A máa ń lò àsopọ̀-agbègbè fún àsopọ̀ kan , èkejì fún ojú-òpó kan.

Ìrísí wọn níí.

```
|bíìtì 10  |       bíìtì 54          |         bíìtì 64           |
+----------+-------------------------+----------------------------+
|1111111010|           0             |      atọ́kùn àfidámọ̀        |
+----------+-------------------------+----------------------------+
```

Àwọn àdírẹ́ẹ̀sì àsopọ̀-agbègbè máa jẹ́ lílò fún àsopọ̀ kan láti ṣègbékalẹ̀ àdírẹ́ẹ̀sì aládáṣe, tàbí ìdámọ̀ agbègbè tí a ò bá lò alànà.
Alànà kan kò lè fi èdìdì ránṣẹ́ sí orísun àdírẹ́ẹ̀sì àsọpọ̀ agbègbè tàbí sí èbúté omìí.

Ìrísí àdírẹ́ẹ̀sì ojú-òpó agbègbè

```
|bíìtì 10  | bíìtì 38    |bíìtì 16            |     bíìtì 64 bits  |
+----------+------------+-------------------------------------------+
|1111111011|     0      | Àfidámọ̀ àsopọ̀ abẹ́nu  |                    |
|          |            |      Subnet ID      |    àfidámọ̀ atọ́kùn   |
+----------+------------+-----------+-------------------------------+
```

A máa lò àdírẹ́ẹ̀sì ojú-òpó agbègbè fi tọ́kasí atọ́kùn nínú ojú-òpó làì lò àfomọ́ káríayé.

## 2.6 Àdírẹ́ẹ̀sì anycast

Àdírẹ́ẹ̀sì anycast ni èyí tí a ń lò fún atọ́kùn púpọ̀ ( tó somọ́ kókó púpọ̀ ), àmọ́ èdìdì tí a bá fíránṣẹ́ sí àdírẹ́ẹ̀sì atọ́kùn anycast máa lọ sórí kókó tí kò jìnà tí alànà mọ̀.
A máa pín àwọn àdírẹ́ẹ̀sì anycast láti àwọn ààyè àdírẹ́ẹ̀sì unicast tí a sì máa lò ìrísí àdírẹ́ẹ̀sì tí a ti ṣàlàyé, èyí túmọ̀ sí pé àwọn àdírẹ́ẹ̀sì anycast somọ́ àdírẹ́ẹ̀sì unicast.
Nígbà tí a bá fún atọ́kùn púpọ̀ ni àdírẹ́ẹ̀sì unicast kannáà, èyí máa yípadà sí àdírẹ́ẹ̀sì anycast.
A máa ń lò àdírẹ́ẹ̀sì anycast fún atọ́kùn púpọ̀ tó wà ní àdírẹ́ẹ̀sì unicast kannáà. Kókó tí a fún ni àdírẹ́ẹ̀sì yìí tó yípadà sí àdírẹ́ẹ̀sì anycast láti àdírẹ́ẹ̀sì unicast láti mọ̀ pé àdírẹ́ẹ̀sì anycast ni òun.

Fún àdírẹ́ẹ̀sì anycast tí a lò, àdírẹ́ẹ̀sì àfọmọ́ p kan wà tó gùn jù tí ń tọ́ka sí àgbékalẹ̀ tí gbogbo àwọn atọ́kùn pẹ̀lú àdírẹ́ẹ̀sì anycast somọ́. Lẹ́yìn ìtọ́kasí pẹ̀lú p, alànà láti ṣàfipamọ́ àdírẹ́ẹ̀sì anycast kọ̀ọ̀kan bíi ìwọlé ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ fún ètò alànà ( Tí a ń pè ni ọ̀nà olùpèsè ).
Nígbà tí a bá kúrò ni agbègbè tí p tọ́kasí a lè lò àdírẹ́ẹ̀sì anycast bíi ìkéde ìfisọ́nà aláfomọ́ p.
Nígbà mì ín, tí kò dara, àfomọ́ p lè jẹ́ òdo, tí àwọn ọmọ ìjọ wọ̀nyẹn kò níí ní ibùgbé kan.
Nígbà yẹn a lè kéde àdírẹ́ẹ̀sì bíi ti alànà tó yàtọ̀ lórí íntánẹ́ẹ̀tì.
Èyí fihàn wa bíi tí ìṣàgbékalẹ̀ ní ìdíwọ̀ nínú fún àwọn àdírẹ́ẹ̀sì anycast káríayé, èyí fi yé wa pé àgbékalẹ̀ yìí kò gbọdọ̀ wáyé, tàbí níwọ̀nba.
Ìwúlò àdírẹ́ẹ̀sì anycast ni kó tọ́kasí àwọn alànà tó wà nínú ìjọ olùpèsè lórí íntánẹ́ẹ̀tì.
Èyí tí á fún wa ni àǹfààní lò àwọn àdírẹ́ẹ̀sì wọ̀nyìí bíi àdírẹ́ẹ̀sì agbédéméjì nínú àkọsórí ìfisọ́nà IPV6 fún pípèsè èdìdì nínú àwọn ìpele ọ̀nà. Ìwúlò àdírẹ́ẹ̀sì anycast tó ṣeé ṣe ni tí ìtọ́kasí àsopọ̀ abẹ́nu kan , tàbíti ìjọ àlànà ìfisọ́nà agbègbè kan. A ní ìrírí púpọ̀ fún ìlò àdírẹ́ẹ̀sì anyŋast ní gbogbogbà títí a tún máa ní ìmọ̀ fikun ti àwọn ìṣìrò
Ààyè àfikún

## 2.6.1 Àdírẹ́ẹ̀sì abẹ́nu tó pọndandan

ìrísí àdírẹ́ẹ̀sì anycast alásopọ̀ abẹ́nu alànà tí a ti ṣàlàyé níí.

```
|                     bíìtì n                     |  bíìtì 128-n   |
+-------------------------------------------------+----------------+
|                Àfòmọ́ alásopọ̀ abẹ́nu               | 00000000000000
|              subnet-prefix
+-------------------------------------------------+----------------+
```

Àfòmọ́ àdírẹ́ẹ̀si alásopọ̀ máa ń tọ́ka sí àsopọ̀ àkànṣe. Àdírẹ́ẹ̀sì yìí jẹ́ kannáà pẹ̀lú àdírẹ́ẹ̀sì unicast nínú àsopọ̀ tí ń tọ́kasí tí atọ́kùn tí a fi sí òdo ( 0 ).

Èdìdì tí a bá fíránṣẹ́ sí àdírẹ́ẹ̀sì anycast alànà alásopọ̀ abẹ́nu máa jẹ́ gbígbà fún alànà àsopọ̀ abẹ́nu kan.
Ó pọndandan kí gbogbo alànà lè ní ojú ìkànpọ̀ pẹ̀lú àdírẹ́ẹ̀sì anycast pẹ̀lú àsopọ̀ abẹ́nu tí wọ́n ní atọ́kùn pẹ̀lú.
Lílò
A máa ń lò àdírẹ́ẹ̀sì anycast alànà alásopọ̀ abẹ́nu fún ohun èlò kan tí kókó bá fẹ́ ṣàsopọ̀pẹ̀lú ìjọ alànà lórí àsopọ̀ abẹ́nu tó jìnà.

**Àpẹẹrẹ**
Nígbà tí ẹ̀rọ ìbaraẹnisọ̀rọ̀ alágbéká ní láti ṣàsopọ̀ pẹ̀lú aṣojú ẹ tó wà nínú àsopọ̀ abẹ́nu tó wà nílé.

## 2.7 Àdírẹ́ẹ̀sì Multicast ( Ìtànkalẹ̀ )

IPv6 multicast máa ń tọ́kasí ìjọ kókó, kókó yìí lè jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ìjọ ìtànkalẹ̀.
Ìrísí níí.

```
|   8    |  4 |  4 |                 112 bits                     |
+------ -+----+----+----------------------------------------------+
|11111111|flgs|scop|                 group ID                     |
+--------+----+----+----------------------------------------------+
```

11111111 Máa tọ́ka sí àdírẹ́ẹ̀sì ìtànkalẹ̀

Flgs Ìjọ àsia mẹ́rin

```
+-+-+-+-+
|0|0|0|T|
+-+-+-+-+
```

Àsia ìkẹ́yìn wà ni pamọ́ fún lílò lọ́jọ́wájú.
T=0 ni ìtọ́kasí ìtànkalẹ̀ ìgbà gbogbo ilẹ́ṣẹ́ àgbáyé tí ń fún àwọn Oǹkaye íntánẹ́ẹ̀tì ni fún un.
T = 1 Máa tọ́ka sí ìtànkalẹ̀ àìṣegbogbogbà

Scop Ni oǹkaye ti a máa ń lò fún ààlà òpin ìtànkalẹ̀ tí iye bíìtì jẹ́ 4.
Àwọn oǹkaye nìwọ̀nyìí:

0 Ìpamọ́
1 òpin Kókó-agbègbè
2 òpin Àsopọ̀-agbègbè
3 (àì lò)
4 (àì lò)
5 òpin ojú-òpó agbègbè
6 (àì lò)
7 (àì lò)
8 òpin ètò agbègbè
9 (àì lò)
A (àì lò)
B (àì lò)
C (àì lò)
D (àì lò)
E òpin káríayé
F ( àì lò )

Àfidámọ̀ ìjọ máa ń tọ́ka sí àdírẹ́ẹ̀sì ìjọ multcast yálà tó jẹ́ ti ìgbàgbò tàbí ìgbà díẹ̀.pẹ̀lú ìmọ̀ òpin. Ìtúmọ̀ àdírẹ́ẹ̀sì multicast tí a ń lò, ò níí nǹkan kan ṣe pẹ̀lú oǹkaye òpin.

Bíi àpẹẹrẹ, tí a bá lò àdírẹ́ẹ̀sì multicast gbogbogbà fún àwọn ìjọ olùpèsè NTP (olùpèsè aago) pẹ̀lú oǹkaye àfidámọ̀ $101_{16}$:

FF01:0:0:0:0:0:0:101 Túmọ̀ sí pé àdírẹ́ẹ̀sì àwọn olùpèsè NTP wà lórí kókó kannáà pẹ̀lú alátagbà.

FF02:0:0:0:0:0:0:101 Túmọ̀ sí pé àwọn olùpèsè NTP wà nínú àsopọ̀ agbègbè kannáà pẹ̀lú alátagbà.

FF05:0:0:0:0:0:0:101 Túmọ̀ sí pé àwọn olùpèsè NTP wà nínú àsopọ̀ ojú-òpó kannáà pẹ̀lú alátagbà.

FF0E:0:0:0:0:0:0:101 Túmọ̀ sí pé àwọn olùpèsè NTP wà lórí íntẹ́ẹ̀nẹ́tì.

Àwọn àdírẹ́ẹ̀sì multicast àìṣe gbogbogbà máa ní túmọ̀ nínú agbègbè kan nìkan. Bíi àpẹẹrẹ Nígbà tí ìjọ kaan tí a tọ́ka sí àdírẹ́ẹ̀sì multicast àìṣe ìgbàgbogbo ojú-òpó FF15:0:0:0:0:0:0:101, yàtọ̀ sí ìjọ tí ń lò àdírẹ́ẹ̀sì kannáà nínú ojú-òpó mì ín, ìjọ tí ń lò àdírẹ́ẹ̀sì kannáà nní agbègbè mì ín, tàbí ìjọ tí ń lò àdírẹ́ẹ̀sì kannáà tó jẹ́ tí ìgbàgbogbo.
A ò ní láti lò àdírẹ́ẹ̀sì multicast bíi àdírẹ́ẹ̀sì orísun nínú édìdì IPv6 kan tàbí kó wà lórí àkọsórí bíi àdírẹ́ẹ̀sì ìfisọ́nà.

## 2.7.1 Àwọn àdírẹ́ẹ̀sì àkànṣe

Àwọn àdírẹ́ẹ̀sì multicast tí a mọ̀ :
Àwọn àdírẹ́ẹ̀sì tó wà nípamọ́ :

FF00:0:0:0:0:0:0:0
FF01:0:0:0:0:0:0:0
FF02:0:0:0:0:0:0:0
FF03:0:0:0:0:0:0:0
FF04:0:0:0:0:0:0:0
FF05:0:0:0:0:0:0:0
FF06:0:0:0:0:0:0:0
FF07:0:0:0:0:0:0:0
FF08:0:0:0:0:0:0:0
FF09:0:0:0:0:0:0:0

Àwọn àdírẹ́ẹ̀sì wọ̀nyìí wà ní ìpamọ́ tí a sì ní láti lò wọn fún ìjọ multicast kan.

Àwọn àdírẹ́ẹ̀sì kókó :

FF01:0:0:0:0:0:0:1
FF02:0:0:0:0:0:0:1

Àwọn àdírẹ́ẹ̀sì wọ̀nyìí máa ń tọ́ka sí ìjọ kókó IPv6 pẹ̀lú oǹkaye òpin 1 ( kókó agbègbè) tàbí 2 ( àsopọ̀ agbègbè ).

Gbogbo àdírẹ́ẹ̀sì àwọn alànà.

FF01:0:0:0:0:0:0:2
FF02:0:0:0:0:0:0:2
FF05:0:0:0:0:0:0:2

Àwọn àdírẹ̀ẹ̀sì wọ̀nyìí máa tọ́ka sí àwọn ìjọ alànà IPv6 pẹ̀lú oǹkaye òpin 1 ( kókó agbègbè ), 2 2 ( àsopọ̀ agbègbè ), 5 ( ojú-òpó agbègbè ).

Ìbéèrè fún àdírẹ̀ẹ̀sì kókó :

FF02:0:0:0:0:1:FFXX:XXXX

Àwọn àdírẹ̀ẹ̀sì wọ̀nyìí ni a máa ṣírò sí àwọn àdírẹ̀ẹ̀sì unicast àti àdírẹ̀ẹ̀sì anycast. A máa sẹ̀dá àdírẹ̀ẹ̀sì multicast pẹ̀lú àwọn bíìtì 24 alágbára kékere.Tí a sì ṣàsopọ̀ àwọn bíìtì wọ̀nyìí pẹ̀lú àfomọ́

FF02:0:0:0:0:1:FF00::/104 tó já sí pé àwọn àdírẹ̀ẹ̀sì multicast kúró ni

FF02:0:0:0:0:1:FF00:0000

dé

FF02:0:0:0:0:1:FFFF:FFFF

Bíi àpẹẹrẹ, àdírẹ̀ẹ̀sì ìbéèrè fún àdírẹ̀ẹ̀sì IPv6

4037::01:800:200E:8C6C ni

FF02::1:FF0E:8C6C IPv6

Àwọn àdírẹ̀ẹ̀sì tó yàtọ̀ pẹ̀lú àwọn tó wà láyè gíga, nítorí àwọn àfòmọ́ àsopọ̀ máa wà àdírẹ̀ẹ̀sì Ìbéèrè fún kannáà tí a sì di oǹkaye àdírẹ̀ẹ̀sì multicast ti kókó kan láti dé.
Kókó kan pọn dandan fi ṣe ìṣírò àti fi dé àdírẹ̀ẹ̀sì ìbéèrè fún, fún àdírẹ̀ẹ̀sì unicast àti anycast ti a so ó mọ́.

## 2.7.2 Ìfifún àdírẹ̀ẹ̀sì IPv6 multicast

Ọ̀nà tí a ń lò lọ́wọ́lọ́wọ́ fi fún àdírẹ̀ẹ̀sì multicast ni [ETER] , a máa ṣẹ̀dá IPv6 multicast sínú ìrísí àdírẹ̀ẹ̀sì IEEE 802 MAC. Fún ìdí èyí a máa lò àwọn bíìtì 32 alágbára kékeré ti àdírẹ̀ẹ̀sì multicast; Èyí yàtọ̀ bí a ṣeé ṣe pẹ̀lú [ TOKEN ]. Àwọn àfidámọ̀ ìjọ tí wọn kére tàbí tí wọn dọ́gbà mọ́ bíìtì 32 ni a máa fi ṣẹ̀dá àdírẹ̀ẹ̀sì MAC ẹyọ kan.
Látara èyí a ní láti ṣàgbékalẹ̀ àwọn àdírẹ̀ẹ̀sì tí ìtọ́kasí ìjọ máa sàbá wà lórí àwọn bíìtì agbára kékeré 32, bí a ti fihàn nísalẹ̀.

```
|   8    |  4 |  4 |          bíìtì 80          |     bíìtì 32     |
+------ -+----+----+----------------------------+------------------+
|11111111|flgs|scop|   ìpamọ̀ láti jẹ́ òdo        |    ìjọ Àfidámọ̀    |
+--------+----+----+----------------------------+------------------+
```

Tí èyí bá dí àwọn ìjọ IPv6 multicast gbogbogbà kù dé $2^{32}$ , o lè jẹ́ ìdíwọ lọ́jọ́ wájú tó pọn dandan kí oǹkaye yìí ga fikún, àmọ́ àdírẹ̀ẹ̀sì multicast máa ṣiṣẹ́ tí agbára ẹ ò níí pọ.
IANA ti ṣàlàyé àwọn àdírẹ̀ẹ̀sì multicast mì ín , ó ti sì ṣàgbékalẹ̀ wọn.

## 2.8 Àdírẹ̀ẹ̀sì kókó pọn dandan

Ó pọndandan kí kọ̀pútà dá àwọn àdírẹ̀ẹ̀sì wọ̀nyìí mọ̀ bíi ìṣèdámọ̀ tirẹ.

Àdírẹ̀ẹ̀sì àsopọ̀ agbègbè kọ̀ọ̀kan

- Àdírẹ̀ẹ̀sì multicast kan tí wọ́n fún
- Àdírẹ̀ẹ̀sì ìparíòpin
- Gbogbo àwọn àdírẹ̀ẹ̀sì multicast àwọn kókó

- Gbogo àwọn àdírẹ́ẹ̀sì multicast àwọn kókó ìbéèrè fún , fún àwọn àdírẹ́ẹ̀sì unicast, anycast.
- Àdírẹ́ẹ̀sì multicast  gbogbo àwọn ìjọ kọ́ńpútà náà.

Ó pọn dandan kí alànà kan mọ́ gbogbo àwọn àdírẹ́ẹ̀sì tí kọ́ńpútà kan láti mọ̀ pẹ̀lú gbogbo àwọn àdírẹ́ẹ̀sì àtẹ̀lé nígbà tí ń mọ́ rẹ.

- Àwọn àdírẹ́ẹ̀sì anycast  fún gbogbo àwọn àtọ́kùn tí ìgbékalẹ̀ rẹ láti mọ̀
- Gbogbo àwọn àdírẹ́ẹ̀sì anycast  tí àṣàgbékalẹ̀ wọn pẹ̀lú alànà.
- Gbogbo àwọn alànà pẹ̀lú àdírẹ́ẹ̀sì multicast.
- Gbogbo àwọn àdírẹ́ẹ̀sì multicast pẹ̀lú àwọn ìjọ tó somọ́ alànà.

Àwọn àfòmọ́ àdírẹ́ẹ̀sì tí a ní láti ṣàlàyé wọn níí.

- Àdírẹ́ẹ̀sì tí a ò ṣàlàyé
- Àdírẹ́ẹ̀sì ìpariòpin
- Àdírẹ́ẹ̀sì multicast oní púpọ̀
- Àfòmọ́ agbègbè ( àsopọ̀ agbègbè àti ojú-òpó agbègbè )
- Àdírẹ́ẹ̀sì multicast tí a ti ṣàlàyé
- Àfòmọ́ tó somọ́ IPv4

Gbogbo àwọn àgbékalẹ̀ láti gbà pé kí gbogbo àdírẹ́ẹ̀sì jẹ́ oní unicast kan tó bá jẹ́ ìgbékalẹ̀ àkanṣe ( Bíi àpẹẹrẹ àdírẹ́ẹ̀sì anycast )

## 3  Tí ààbò ń kọ́

Gbogbo àwọn àkọlẹ̀ ò níí ipá tààrà lórí ààbò amáyédẹrùn íntánẹ́ẹ̀tì. Àwọn àlàyé ìfàṣẹsí àwọn èdìdì IPv6 wà lórí [AUTH].

# Àfikún A

## Ìṣẹ̀dá atọ́ka sí atọ́kùn lọ̀nà EUI-64

Ọ̀nà tí a fi ṣẹ̀dá atọ́ka atọ́kùn  ní ọ̀nà EUI-64 jẹmọ̀ àwọn àfidámọ̀ àsopọ̀ àti kókó. A máa rí àwọn ọ̀nà mélòó kan ní wájú.

## Àsopọ̀ tàbí kókó pẹ̀lú àfidámọ̀ EUI-64

Nǹkan tó pọn dandan fi ṣèyípadà àfidámọ̀ EUI-64 sí àfidámọ̀ atọ́kùn ni ká yí bíìtì “u” ( káríayé / gbègbè ) padà.
Bíi àpẹẹrẹ àfidámọ̀ EUI-64 kan ní àgbáyé ní ìrísí tó jẹ́

```
|0              1|1              3|3              4|4              6|
|0              5|6              1|2              7|8              3|
+----------------+----------------+----------------+----------------+
|cccccc0gcccccccc|ccccccccmmmmmmmm|mmmmmmmmmmmmmmmm|mmmmmmmmmmmmmmmm|
+----------------+----------------+----------------+----------------+
```

Nígbà tí “c” jẹ́ àwọn bíìtì ti iléṣẹ́ kan, “0” ni oǹkaye ti bíìtì ( káríayé / agbègbè ) tí ń tọ́ka sí gbogbo fífò, “g” sì jẹ́ bíìtì ( olúkúlùkù / ìjọ ) , ti “m” jẹ́ bíìtì iléṣẹ́ ẹlẹ́rọ ́fidámọ̀, ti àfikún àkànṣe, àfidámọ̀ atọ́kùn IPv6 máa ní ìrísí yìí.

```
|0              1|1              3|3              4|4              6|
|0              5|6              1|2              7|8              3|
+----------------+----------------+----------------+----------------+
|cccccc1gcccccccc|ccccccccmmmmmmmm|mmmmmmmmmmmmmmmm|mmmmmmmmmmmmmmmm|
+----------------+----------------+----------------+----------------+
```

Nǹkan ẹyọ kan tí á ṣe fi yípadà ni bíìtì ( káríayé / agbègbè ).
Àsopọ̀ tàbí kókó pẹ̀lú MAC IEEE 802 48 bíìtì [EUI-64] ṣàlàyé ètò kan , bí a ti lè ṣẹ̀dá àfidámọ̀ EUI-64 pẹ̀lú àfidámọ̀ 48 MAC.
A máa ṣàfibọ̀ báìtì méjì pẹ̀lú kíka oní mẹ́rindínlógun tí oǹkaye wọn jẹ́ 0xFF àti oxFE láàrin MAC bíìtì 48 ( láàrin àfidámọ̀ tí ilé̩ṣẹ́ fún ) bíi àpẹẹrẹ le MAC bíìtì 48 pẹ̀lú fífò káríayé.

```
|0              1|1              3|3              4|
|0              5|6              1|2              7|
+----------------+----------------+----------------+
|cccccc0gcccccccc|ccccccccmmmmmmmm|mmmmmmmmmmmmmmmm|
+----------------+----------------+----------------+
```

Nígbà tí àwọn “c” jẹ́ àwọn bíìtì fún “0” jẹ́ oǹkaye bíìtì ( káríayé/ agbègbè ) tí tọ́ka sí òpin lápapọ̀, “g” jẹ́ bíìtì olúkúlùkù fi tọ́kasí fífò káríayé, tí “m” sì jẹ́ àwọn bíìtì tí atọ́ka àfikún iléṣẹ́, ìtọ́kasí atọ́kùn máa jẹ́.

```
|0              1|1              3|3              4|4              6|
|0              5|6              1|2              7|8              3|
+----------------+----------------+----------------+----------------+
|cccccc1gcccccccc|cccccccc11111111|11111110mmmmmmmm|mmmmmmmmmmmmmmmm|
+----------------+----------------+----------------+----------------+
```

Nígbà tí àwọn àdírẹ́ẹ̀sì MAC IEEE 802 bíìtì 48 bá wà lórí ( atọ́kùn tàbí kókó ) àgbékalẹ́ láti lò wọn fi ṣẹ̀dá àfidámọ̀ atọ́kùn látàrí pé wọ́n ò pe méjì.

**Àsopọ̀ pẹ̀lú àwọn àfidámọ̀ tí kìí ṣe káríayé**

Àwọn àsopọ̀ mélòó kan wà tí wọn bá jẹ́ oníwọ̀lé púpọ̀, wọn ò níí àfidámọ̀ káríayé àkànṣe kan. Bíi àpẹẹrẹ LocalTalk àti arcnet. Ètò láti ṣẹ̀dá atọ́ka pẹ̀lú EUI-64 ni ká lò àfidámọ̀ àsopọ̀

```
|0              1|1              3|3              4|4              6|
|0              5|6              1|2              7|8              3|
+----------------+----------------+----------------+----------------+
|0000000000000000|0000000000000000|0000000000000000|0000000001001111|
+----------------+----------------+----------------+----------------+
```

A máa ṣàkíyèsí pé bíìtì káriayé / agbègbè wà ni “0” fi ṣàtọ́kasí òpin agbègbè

## Àsopọ̀ láìsí àfidámọ̀

Àwọn àsopọ̀ mélòó kan ò níí atọ́kasí, àwọn èyí tí a mọ̀ ni àwọn àsopọ̀ àtẹ̀lé , àgbékalẹ̀ ọ̀nà abẹ́lẹ̀. A ni láti yàn atọ́ka yìí lọ́nà kan.
Nígbà tí àfidámọ̀ ìṣèfibọ̀ kò bá sí lórí àsopọ̀ kan, a máa lò àfidámọ̀ káríayé ti atọ́kùn mì ín, tàbí èyí ti a fún kókó náà gan an. Nítorí náà atọ́kùn kan tí a somọ́ àsopọ̀ yìí ò gbọdọ̀ lò àfidámọ̀ kan tí a ti fún kókó mì ín.

Nígbà tí kò bá sí àfidámọ̀ atọ́kùn káríayé ni ìlò, àgbékalẹ̀ máa ṣẹ̀dá atọ́kùn agbègbè òpin àfidámọ̀. Nǹkan tí a ń béèrè fún ni kó máa pé méjì lórí àsopọ̀. Ọ̀nà pọ̀ tí a ń fi yàn àfidámọ̀ atọ́kùn ẹyọ kan. Bíi :

1. Àgbékalẹ̀ ti a ṣé pẹ̀lú ọwọ́
2. Ìṣẹ̀dá àwọn nọ́nbà lọ́nà rúdúrùdù
3. Oǹkaye àtẹ̀lé kókó.